# EKO AKETE.

IWE IROHIN ỌSỌSẸ.

ỌRỌ IFOJUSUN:—

"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI".—W. T. STEAD.

VOL I. NO. 29. SATURDAY, JANUARY 27, 1923. FOURPENCE.

*Editor & Proprietor:*—
ADEOYE DENIGA,
*Office:* 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.


ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor.*

## GBOHUN-GBOHUN.

### KITOYI?

Ninu Iwe-irohin ọsọsẹ ti Ijọba ti ọjọ 18 oṣu yi, a ri ka ninu ọrọ Gomina Agba pe on npete ati fi Ejidilogun-din-ọgọrun Ọkẹ pọnwun (£35,000) sapakan fun nina nipa ṣiṣe eto ti nkan ti Nigeria yio fi ṣọwọ si ilu Gẹsi fun Ifihan-nkan gbogbo Ilu to wa labẹ Asia Ọba *King* ni agbaiye, ti nwọn fẹ ṣe ni ọdun to mbọ (1924) o si tun sọ pe on yio bu kun owo na ti ko ba to. Ẹnyin ara ilu, ọrọ re o!

A ko ro pe Gomina ti da ọrọ na sọ fun ajọ Igbimọ-Aṣofin larin wa nibi siwaju, biotilẹjẹpe a wi fun ni pe a ni Enia Dudu meji nibẹ ti Ijọba tikalarẹ yan pe awọn ni nṣoju wa. A ko sọ pe nina owo si irufẹ nkan tian-tian yi buru, ṣugbọn ohun ti a nsọ ni pe kiniṣe ti Ijọba ko tete fi Imọ Ilu si ni ọna ti a wi yi, ki gbogbo awọn *Member* Ijọ-Igbimọ-Aṣofin ti a sọ yi, ti dudu ti funfun le mọ bi owo na pọju tabi ko pọju,—gbogbo wa ni a sa mọ bi ode ti le si nisisiyi ko to di pe Gomina sọ sode gbayawu bayi. A ko mọ bi eyi jẹ aṣa ilu miran, ibaṣe ilu Aganyin, tabi ti Saro, tabi ti Gambe

Gbogbo wa t'oyinbo t'enia dudu lo sa njọ dawo si apo Ọba ninu eyiti Gomina npete ati mu ogidi-nleje owo yi lai kọkọ fi imọ ajọ Igbimọ ti a nwi yi si. Eyi ku diẹ ki-a-to

A npetę ati yi ọrọ Gomina na pada si Ede wa ki a si tẹ ẹ sinu Iwe-irohin yi ni ọsẹ to mbọ.

## A MBEKE MỌ, ARA NFU WỌN.

A dupẹ lọwọ ọrẹ wa kan ti o fi Iwe-ọdọdun ti awọn Oyinbo Ọlọkọ *Elder Dempster* ti ọdun Keresimesi to kọja han wa: ninu awọn Aworan ti npani lẹrin diẹ ti a ri, ni ti Ọgbẹni *Lawyer* SHYNGLE, *Lawyer* Akere-koro yi fẹ ọla t'on ti Sarotu-Arowoṣefuja to nmu. A ko ri Aworan awọn Lagbaja ati Temado ti nwọn npe ara wọn ni nkan gunmọ lọdọ Oyinbo ninu iwe na: a ni lati sọ fun awọn enia wa pe awọn to ba jẹ pataki ni ilu loju awọn Oyinbo ni a nyà ni ọna ipanilẹrin bayi: ẹniti o ba wo Iwe na yio ri Aworan awọn Ijimi oyinbo bi *Bishop* JONES, Ojiṣẹ-Ọlọrun GRIFFIN, GOMINA LUGARD, Ọgbẹni MAIDMAN, *Lawyer* DAVIES ati awọn Jakan-Jakan miran lẹgbẹ Aworan ti Ọgbẹni SHYNGLE: ṣugbọn a wa ti awọn "ara-ile-wa" ti nibẹ: ẹ o ṣe iranti Aworan ti Ọgbẹni Aṣọ-ọdan (*Race Course Cole*) ti a ṣe ni ọna yi, ti o si han ninu Iwe-irohin *West Africa* ti ọdun to kọja. Ọgbẹni Oyinbo ti o npe ara rẹ ni SEEHE ni o nya awọn Aworan iyebiye yi.

## OWO A-FUNA O!

Ọbanikoro Oloye se Ase-Akanṣe kan ninu Afin rẹ ni *Saturday* to kọja, eyi ti o pe awọn gbajumọ si lati agogo marun alẹ titi di agba-rọ alẹ ọjọ na: Ero nwọ bi omi.

## "EMI YIO SỌ NYIN DI APẸJA ENIA."

Awọn Ijọ ti a npe ni "Ṣọṣi Ẹlẹja" nṣe Ayadun karun wọn ni Ile-isin wọn ni Ibode-lailai lati *Monday* ọsẹ yi titi yio fi di ọjọ keji oṣu ti o nbọ: A ba wọn yọ Aṣeyi Ṣamọdun.

## A RI IDIN NI'YỌ!!!

Anu ṣe ni lati sọ pe ni iwọn agogo mọkanla arọ ọjọ *Wednesday* ọsẹ yi, a ri Ọgbẹni Oyinbo Olori Ọlọpa MOOREMAN ati Ọgbẹni Olori igba-keji rẹ REIS lọ mu Lọya KOLAJO DOHERTY ni ile rẹ ni Itẹ Balogun fun ẹṣẹ ti a ni o ṣẹ Ofin: a mu lọ si Sabu Ọlọpa, a si duro fun u nibẹ. Ẹjọ ti a nba lọya yi ro ni pe o ji £1,216 3 ni *October 1921*, lara owo Hausa kan ti a npe ni Al Hasan Dantata ara Kano. Ẹjọ sun titi di agogo mẹwa abọ ọtunla (*Monday*) Lọya THOMPSON ati ALAKIJA ni yio ba ṣe ẹjọ na.

## ỌBA ALAṢẸ EKEJI ORIṢA.

Gomina agba yio dakan lọ si Ibadan ni ọjọ kejila oṣu to nbo fun Ifihan ohun ọgbin ti nwọn fẹ ṣe nibẹ.

## ABỌ O!

A ki Ọgbẹni wa J. H. Doherty "kabọ" lati ilu Saro nibi ti o ti lọ lenu oṣu meji kọja Alafia kẹ de?

## ALUFA J. A. LEIGH, PẸLẸPẸLẸ O!

A gbọ pe awọn Ijọ Jordan, ti Oke Suna fi Alufa wọn, Ẹni-ọwọ J. A. LEIGH, sun ẹsun gbọro-gbọrọ kan lọdọ awọn Alaṣẹ Ijọ C.M.S.: o dabi ẹnipe ọrọ na yi Alufa na lọwọ diẹ, nitoripe a gbọ pe awọn Alaṣẹ nia fi aṣẹ wọn lelẹ pe ko gbọdọ da owo kan nia si nkan ti Ṣọṣi na mọ tabi ki o tun daṣe ohun to jẹ mọ iṣẹ na ni ọna miran, lai pe Ijọ Oni-dunkun-oyinbo (*Breadfruit Church*) lọwọ ninu rẹ.

## ỌWỌ A RAN O!

A ba awọn ọmọde-mẹsọ Doctor wa Dr. Akinọla Maja ati Dr. J. C. Vaughan yọ fun "Ile-alarun" titun ti wọn ṣeṣẹ ṣọwọpọ ṣi ni ita Igboṣere ni ọjọ *Tuesday* ọsẹ yi.

Ẹni ọwọ A. N. Cole lo gba akanṣe adura ti a fi ṣi ile na, o si tun gba adura Ibukun nigbati a pari aṣẹyẹ na, Dr. Ogunlola Ṣapara ẹbọra-ninu-iṣẹ-gbigba-ẹbi-ọmọ, lo ṣi Ile na, diẹ ninu awọn to sọrọ nibẹ ni Ọlọla Dr. O. ỌBASA ati PETER J. C. THOMAS, awọn Dr. miran wa sibi ẹyẹ yi ati awọn Oloye-oni-fila-funfun.

## GBA WERE NGO GBA WERE!!!

Awọn ẹgbẹ Ijiyan ti Ile-iwe giga *C.M.S. Grammar School* ṣe Ipade Ijiyan wọn ni *Thursday* ọsẹ yi, ni gbangan ile-iwe na. Ohun ti nwọn jiyan le lori ni pe "Awọn ti ki muti lo ntubọ gbe awọn ara ilu ga ju awọn "ori-kana-tu'rungbọn yẹu" lọ.

Ọgbẹni MAJEK. AKINLOYE lo wa fun apa ekinni Ọgbẹni J. LUCAS wa fun apa keji.

## Correspondence.

Abeokuta, 17/1/23.

The Editor of "Eko Akete"
Lagos.

Dear Sir,

I have read and re-read Rev. M. S. Cole's Xmas message to us his country-men, in the Xmas number of the African Messenger. The article is indeed a great food for thought.

The time has come that our patriotism should be shown in practice and not in theory only. We want liberal education; we want encouragement and unaminity. Amongst the Europeans, prizes and even titles are given for invention or any new production for the education and the welfare of their people and race, but ours is just to criticise and discourage. It is high time we leave off all foolishness and act wisely.

I admire your zeal and courage and your disinterestedness in the race. That you have been labouring single-handed and under great odds cannot but win for you a great respect. But, thank God, that some of us are beginning to realize the duty becoming every one of us, in the interest of our race, by giving a practical support for the furtherance of your paper. May such supporters increase by leaps and bounds.

I wish to suggest the establishment of "Native Production Appreciation Fund" i.e. that any Native Productions which tend to the progress of the Race should, if approved by the Committee controling the Fund, be awarded prizes.

Some years ago (1910 perhaps) Mr. E. D. Morel was the recipient of an appreciation (in monies contributed even by us) a/c of his denunciation of the Congo Atrocities. What have we done to our Editors for fighting our causes?

What have we done to encourage our own Authors, Poets and Skilful Artisans? On the contrary we decry them; we throw mud at them.

Please bestir the public to think seriously over the above suggestion and let us see that something however little is done this year.

Yours truly,
A. K. A.

## Open Letters.

TO CELEBRITIES IN DIFFERENT WALKS OF LIFE.

To Drs. AKINỌLA MAJA, M.B., CH.B. (Edin:)
AND JAMES CHURCHILL VAUGHAN, M.B., CH. B (Glasg:) D.T.M. (L'vpool.)
Garber Square, and Victoria Street, Lagos.

Beloved Physicians, No. 17.

Congratulations on the success which crowned your efforts to pull together, in recently opening, on Tuesday last, a Union Hospital at 24, Igboṣere Street, this city for the relief of suffering humanity.

Would you mind going a step further, in the near future, to found a monthly paper, say, for example, THE NIGERIAN MEDICAL JOURNAL, as a sister-organ to THE NIGERIAN LAW JOURNAL, in which our reading public will still have the benefit of your Research, in Pathology and Therapeutics?

By this latest endeavour of yours, you have answered the well-known Shakespearian Question "Canst thou not minister to a mind diseased?" to the letter.

Good Luck, old Chaps!
EKO AKETE.

## THANKS FOR SYMPATHY.

MR. C. P. WILLIAMS and familiy hereby return their sincere thanks to all those who by their personl calls, Letters, Telegrams, and otherwise have expressed sympathy with them on the "Home-call of their beloved mother, ZENOBIA C. WILLIAMS, on Saturday the 13th instant.

# EKO AKETE.

Eko, Saturday January, 27, 1923.

## F'ONIJA SILẸ, GBA'LAPẸPẸ LOJU.

A mọmọ dakẹ lati ọjọ diẹ sẹhin lai sọ si irufẹ Esi ti Gomina-agba Sir Hugh Clifford fi si ọrọ Eşugbayi Eleko Ọmọ-Alade titi ao fi da iwe-esi ọrọ na sinu iwe irohin yi: ẹ o si ri pe a şe eyi lati ẹnu ọsẹ to kọja lọ ba ọsẹ yi.

Nigbati a ka iwe na siwa-sẹhin, sọtun sosi, o jẹ ohun ti o dun ni gidigidi pe kàkà ki Gomina fi esi bi Ọmọluwabi pe ọrọ na ko şēşe mọ, ēbu lo koti Ọgbẹni Shyngle ati awọn "ẹru" Ọlọrun miran, laisẹ lairo ju pe nwọn nbẹbẹ lọdọ rẹ fun Eleko lọ: kosi ẹniti irufẹ ède alufaşa bayi ko ya lẹnu, gidi pā, awọn ti nwọn nba Eleko şe "koko-a." Nigbati ẹniti a pe ni Olori gbogbo ilu Nigeria to si jẹ Aşoju Ọba *King*, ẹni, to jẹ pe nipa ipo-nla rẹ o ni lati jẹ Baba Eleti-gbaroye ogunlọgọ awa "ọmọ" to wa labẹ rẹ nibi, ba şẹ sọ ara rẹ di ẹni pala-nta ati ẹni yẹpẹrẹ bayi, nipa mimu to mu gbogbo awọn ẹgbā-gbeje enia to nbẹbẹ fun Eleko lọdọ rẹ ni "abori-wẹrẹ" nipa ọrọ-koba-kun-gbe to sọ fun awọn agba-lagba onile-ọlọna bayi, ẹ ko şai mọ pe ẹyẹ ati ọla tan lara oniwakiwa bayi.

O şẹ ndi igbagbogbo ti irufẹ iwa yi nşẹlẹ: bẹna-ni ni *Wednesday* ọjọ 29 oşu *December*, ninu ọdun 1920, o le ni ọdun keji nisisiyi, ni Gomina wa yi ko ēbu ti awọn enia wa ti nwọn jẹ Igbimọ Ẹgbẹ *Congress*, nigbati nwọn wa ni *London* fun ọrọ pataki ti Ilọsiwaju wa gẹgẹbi ọmọ abẹ Asia George Ọba, ibaşe ni Nigeria, ni ilu Aganyin, ni Saro tabi ni Gambe: yẹyẹ wo ni Gomina wa ko şe tan nigbana? Ko ni bi awọn enia wa ti a nwi yi ba gboju-gbaiya ki nwọn lọ si ilu awọn Ajẹnia ni Mushin, ninu igbo-didi *Nigeria*, lati lọ sọ ọrọ wọn nibẹ, bi awọn Ajẹnia na ko ni fi "ori wọn bọ ifa"? Ati gbogbo ọrọ kọrọ iwọnni ti pupọ ninu wa ko gbagbe di oni-oloni. Awa Yoruba ni nma npowe pe "A ki gbe erin sori ki a tun ma fi ẹsẹ wa irẹ nilẹ, eyini ni pe ko yẹ ki a ba ọnipo-giga ninu nkan ti o jù lọ, tabi ninu kọlọkọlọ awọn ọmọde: nitorina lo şe yẹ jọjọ fun Gomina wa lati şe pẹlẹpẹlẹ ki Araiye ati Ara-ọrun ma ba sọ lorukọ. Kini "anfana" baba ti ki fi ẹmi suru ati ipamọra ba awọn ọmọ rẹ lo? Melomelo ni fun enia ti o wa ni ipo Olori odidi ilu kan bi tiwa?

Enyin Ọgbẹni Shyngle ati Bọkinni ti Gomina fi iwọsi yi lọ, a bẹ nyin, ẹ fiyedenu ki ẹ si fojufo iwa afojukamọ yi da, Ilu dupẹ lọwọ nyin fun işẹ ti ẹ şe nitori Eleko ti ẹ si ti itori na gba ògbó lọwọ Gomina: Ẹ fi awọn Agb'ẹhin-b'ẹbọ-jẹ silẹ, ẹ jẹ ki nwọn mā jẹ ki wọn mā mu, awọ wọn nbẹ l'aka. Ẹni bẹ ni tẹ ni.

K' Ọba *King* pẹ titi.

---

## O KARE!

Ọgbẹni Stanley Benjamin şe dara-dara ni ilu Oyinbo ninu Idanwo rẹ ikẹhin fun işẹ Lọya. Gbere, da-nsaki!!!

---

## KỌTUN WẸ OSI K'OSI WẸ ỌTUN NI ỌWỌ ŞE NMỌ.

O jẹ ohun ti a ba kiyesi pe ami irẹpọ ko f' ara han tobẹ ni arin awọn Ijọ wa ni Abẹokuta gẹgẹ bi a ti yọda ni ipade nla ti Lambeth, o jẹ ohun ti o nmu işiri wa lati ma pe awọn Alufa Ijọ miran lati wa şe iwasu ni akanşe isin bi ti Ikore. Awọn ara Eko gbadun aşa yi a si ni ero pe ire nt'inu rẹ jade fun wọn. Kini şe ti eyi ko ri bẹ ni Abẹokuta? Mo to l'ẹnu t'emi n ọpọlọpọ fi şe isin Ikore ti o kọja yi. A ireti pe a ko ni pẹ mu ẹmi ki olukuluku r bojuto tirẹ lọna bi eyi kuro larin wa.

" Ẹ jẹ ọkan bi emi ati baba mi ti jẹ ọ

Igbẹhin-adun, Abẹ

## MAṢINI TO NKẸ RIRI !!!

Ọgbẹni ARNOLD SCHLESINGER,

Jamani Oniṣowo ara Hamburg, ṣẹṣẹ ṣi awọn ojulowo Ẹrọ-Iranṣọ ti Ọlọwọ ti a npe ni MUNDLOS" nille-Ọja rẹ ni No. 7, Ita Labinjọ leti Ita Williams l'Eko.

Awọn Maṣini wọnyi wa fun kiko giri ni owo pọ ọ. Awọn Maṣini Mundlos wonyi jẹ eyiti a ti npe n " *Original Victoria* " ri, awọn si ko ẹra kan ninu awọn Ẹrọ-Iranṣọ ti nwọn dara jọjọ: Nwọn ko kẹrẹ ninu awọn Maṣini atata ti ilu Jamani.

A o si fun ẹnikẹni to ba ra ninu wọn ni awọn eroja wọn wọnyi, awọn nkan bi,

*Hemming foot*, *Feller*, *Braider* ati *Trimmer*, awọn bi *Steamer*, *Ribbon binder*, *Oiller*, *Ruffler* ati *ribbon fastener*.

Ti iwọ ko ba le wa, kọwe ranṣẹ si Apoti-Ipin we wọn ni Ile-Ipinwe, No. 459 l'Eko. A o si fi Iwe Aworan Maṣini na ṣowọ si ọ.

E tete ranṣẹ, bi bẹkọ, Ẹran nyin yio bi Obukọ

---

## FOR SALE.

One Royal " Enfield " Motor Cycle, L. 690.
In good and working condition.

For Particulars

Apply to Mr. S. A CLAY, 1, Macaulay Street,
Or at 75, Ọdunfa Street, Lagos.

---

## Ẹ-WA RA ỌPỌ ỌJA

Ọgbẹni D. B. OṢUNTOLU, oniṣowo Ọlanrewaju ni ọpọlọpọ ọja fun tita ni Ṣabu rẹ ni No. 44 Balogun Street, l'Eko.

Ninu awọn ọja rẹ ni iwọnyi:—Ikoko taba, Carpets Panu ikẹle, Aṣọ oniruru, Itẹko, Baranjẹ, Olowonyọ, Yọmini, ( *Satten* )

Ati orişirişi nkan atata miran, Ọja Ọgbẹni yi rọju o si lere ninu, ọpọku-ọyọku ni.

Ẹ lọ ra ti nyin nibẹ.

---

## WHAT IS MORE REFRESHING

than a sound sleep on a comfortable Bed? or time-saving than a thoroughly good sewing-machine?

A large consignment of Brass Iron-Beds, Bedsteads, (new arrivals from Germany.) hand and Treadle-sewing machines "Gritzner" is just to hand at Mr. Duro. Thomas's establishment 55, Massey St., Lagos.

An early call at this address for your selections will well reward your labour.

Prices attractive and alluring.

CALL TO-DAY NOT TOMORROW.

---

## KILO NGBE MI LỌ YI O? ORUN!

AṢỌ NYIN FAYA, Ẹ LỌRAN.
AṢỌ NYIN FAYA, Ẹ LỌRAN.

IBUSUN-ILESANMI ati
MASINI-A-NJUWON
"Ọgbẹni DURO THOMAS."

Oniṣowo-towolawi, ni awọn IBUSUN mèrémèré onidẹ to ṣẹṣẹ de fun u pẹlu awọn MAṢINI iranṣọ ti a npe ni *Gritzner* ti ọlọwọ ati ti ẹlẹsẹ, lati ilu Jamani wa fun tita ni Ile Ọja rẹ 55, Ita Mãse leti ita Faji, l'Eko.

Ifà mbẹ fun awọn to ba tete lọ ra tiwọn nibẹ: owo yẹpẹrẹ ni a nta wọn, bẹni awọn Ọja na si " ka 'yin " to.

Ẹ lọ ba Àwúre nyin pade nibẹ.

## IWE TI GOMINA KỌ.

Ohun kan pẹlu ti ko tun jẹ ki a le ka Iwe Ẹbẹ yi si ni pe, ọpọlọpọ awọn ti o jẹ olorukọ li Eko, ti nwọn si ti nsọrọ odi gidigidi ni akoko kan si Ijọba, nwon kọ lati fọwọsi i, tabi ki a darukọ wọn mọ ọ lọnakọna.

Nigbati a nfi idahun si Iwe ti mo wipe a fi ki mi kabọ nigbati mo ti Ilu Oyinbo pada, mo paṣẹ fun Olori Sẹkitẹri ti Ijọba ki o fi esi bayi :—

"Ni ori karun Iwe nyin, ẹ mẹnukan ọran ti Eṣugbayi ti a ti mọ bi Eleko ri, ẹniti a ti nyẹ si di lọlọ yi bi Olori Ile Docemo. Mo ni sọ pe, kelẹkẹlẹ ọran na ki ṣe ohun ti ẹ ko mọ daju Niwọn ọsẹ diẹ lẹhin ti Gomina gunlẹ si Nigeria, ati li akoko ti o sare yi iluka lọ, Eṣugbayi ṣe aṣemaṣe kan ti o mu Mr., ti a npe ni Sir Alexander Boyle nisisiyi, ẹniti nṣe adele Gomina nigbana lati rọ ọ loye fun igba diẹ Nigbati Gomina pada de Eko, o wadi ọran na kinkini: pẹlu bi awọn ọrẹ Eṣugbayi papa ko ti ri ibi foran na gbe e, Gomina pinnu lati n si ipo oye rẹ padi; ṣugbọn o'tikara rẹ kilọ fun u lẹsẹkẹsẹ li akiwọdenu loju awọn Onifila Funfun pe a ko ni fọwọgbẹnderẹ mu ọran rẹ mọ bi o ba tun jẹ ki a ri aṣiṣe bẹ lọwọ rẹ.

Laito oṣu melo kan lẹhin ti a kilọ fun u bayi tan ni ẹnikan, ti Eleko ti a yọ loye yi gbe Ọpa rẹ le lọwọ lati sọ fun Ijọba, ti o si lo yọ ọ gelegan si gbangba ni ilu Gẹsi (boya ni adabọwọ ara rẹ ni tabi bi on pẹlu Eṣugbayi ti dimọlu tẹlẹ ni) ti o si nṣe apọnle rẹ de oju apọnpa; okan ninu rẹ li eyi pe, Eṣugbayi ni olori awọn Ijoye ti mbẹ ni Nigeria. Bi eyi ti jẹ ọrọ agbere ti o pa ni lẹrin iyangi to, Gomina ro pe ki ṣe ohun ti a ba ṣeṣẹ ma la ye nyin; ṣugbọn mo ni sọ pe, bi o ba tilẹ sọ pe on ni Olori awọn Ijoye ni ile Yoruba nikan laijẹ pe ti gbogbo Nigeria, Ijọba iba ni lati bu ẹtẹ lu ni gbangba to bi nwọn ti gbe ọran na yọ si gbangba nitori Ijọba yi ni Ijoye bi Ọni Ifẹ, Alafin Ọyọ, Alake Abẹokuta ati Emir Ilọrin labẹ rẹ. A ke si Eṣugbayi nitorina pe ki o lu agogo ki o si sọ pe on ko noga de ipo ti nwọn npolowo rẹ fun on yi bi o tilẹ jẹ pe aṣẹ rẹ ni tabi ti rẹ kọ ni ẹniti o gbe Ọpa rẹ le lọwọ yi fi nkede bẹ. Ko si sisẹ ninu otitọ yi pe ki ṣe pe a kede nikan ni ṣugbọn a tilẹ tẹ ẹ sinu iwe irohin. A si fi han Eṣugbayi bi ajiṣẹ-ijọba pe a ṣe ikede yi a si tẹ ẹ kiri; sibẹ o kọ lati fawọsẹhin ninu ọran na tabi ki o sọ pe on ko mọ idi rẹ. A tẹ ẹ mọ leti, ki ṣe lẹkan pere, ṣugbọn ni ọpọlọpọ igba, bi ojiṣẹ-ijọba ati laṣiri ohun ti kiko rẹ yi le wu jade fun u O le jẹ pe awọn onijamba ti o nkọ ọ li o yi lokan pada pe ko si ewu fun u bi o ba ṣa ka Ijọba si; ṣugbọn mo ni ti kun u pe bi o ti wu ki eyini ri, a tenu mọ ọ fun u to de oju kasinkan ohun ti agunla rẹ yi yio wu jade. Yio si ni lati ma fori ara rẹ ru ohun ti ọran ti a la silẹ yi wu jade fun u. Sẹkitẹri Alaṣẹ ni Ilu Gẹsi si fọhun ti ko ni kọlọkọlọ si pe ohu[n] Gomina ṣe nidi ọran yi tẹ on lorun. Ọba "Kin[g]" papa si ti kọ lati gba Iwe Ẹbẹ nitori Eṣugb[ayi] lẹhin ironu ọran rẹ li arojinle."

Ọrọ wọnni daju to, nwọn si han kedere, ẹnu y[a] mi; anu si ṣe mi pe, ẹnikẹni ti a ro pe o ni ọgbọ[n] o si jẹ ẹni ọwọ le fi akoko ṣofo ki won si ko o[w]o danu fun oṣu mejila lati ṣiṣẹ gba oruko sinu Iw[e] Ẹbẹ ti awon papa ko le ṣe alaimọ pe omulẹmọ ni yio jẹ, ati pe, nitorina, ko to ohun ti a ba [...] apọn le lori fun iṣẹju kanṣoṣo, tabi ki a na kọ[...] kanṣoṣo le lori.

Nitori gbogbo ohun ti mo sọ ninu iwe yi, [...] kọ lati gba Iwọ ti o wu ki a ran si mi lati bẹbẹ[...] ki a tun gba ọran Eṣugbayi.

Ki a sọ eyi fun Ọgbẹni Shyngle ati awọn t[i] fọwọsi iwe pẹlu rẹ, ki a si sọ fun wọn pẹlu [...] iwe-kiwe ti a ba kọ lẹhin eyi si Ijọba nitori pe [...] ki a le mu Eṣugbayi pada si Ipo Olori Ile Doce[mo] a ki yio dahun si rara, a ki yio tilẹ wipe a ri i g[ba].

HUGH CLIFFORD,

*Governor*

*December 30th, 1922*


## SOMETHING TO YOUR TASTE.

MR. J. D. ỌLAYAHA, Painting Contractor a[nd] General Decorator is prepared to undertake a[ll] paint-works of every description to the entir[e] satisfaction of Clients.

He is also an expert in sign-board work : h[e] worked for many important European Firms [in] town notably, the Firm of P. Z and also the lo[cal] P. W. D.

Terms reasonable.

For particulars,

Apply at 16, Mọgaji Lane, Ẹpẹtẹdo.

A trial will convince you

29, Oripasan Lane,

King's Quarter, Isale Eko,

Lagos, Niger[ia]

THIS IS TO CERTIFY THAT I have many years' experien[ce in] Dirty Window Cleaning, Changing of Plan Window to [any] colour or kind of Pattern in Flowers cleaning or w[ashing] washing of wall to any kind as Distemper colour [...] Cleaning and Washing of a Dirty House to new, by Var[ious] and assorted kinds and Pattern of Colour to Paint H[ouse] and putty and painting of Corrugated roof to red.

For Terms, etc, apply to the above address.

**Lawani T. Mogaji,**

*General Manager.*

22, Apatira Street, and
34, Palm Church Street,
Lagos, 6th January. 1923.

I beg to inform the public in general that I am now a Headman of "Esu" in Lagos, for everybody who wishes to join same; it commences from 10/- to £5 every Calendar month from any one who wishes to join same; as long as you can subscribe it is only for six months, before you can receive your share and six pence will be my commission on £1. 0 0.

2. And another commences from 1/- to 10/- every week for any one who wishes to join the "Esu" for three months before you can receive your share and my commission will be six pence on £1 0 0.

3. I may bring to your knowledge again that if you keep long in "Esu" and you want some amount to use, I will help you before you finish your share.

4. I get a certain amount for it to start same, if anybody wishes to join this "Esu" he or she should see me at 22, Apatira Street, or 34, Palm Church Street, Lagos.

*Another due date for the above is 31st January 1923.*

ABUDU WABI BAJELA.

"VESTA"

Treadle Sewing Machines for sale at same address. Prices moderate.

---

ỌMỌ NI YIO ṢEHIN DE E.

"Ẹwa wo" "POSI Alarabara"

Ile Igbẹhin lọdọ J. T. COLE,

Gbẹna-gbẹna ni ita 40, Ofin Canal,

Ihin ko to afojuba

A le gbani ni awin ti a ba san idaji owo.

EMANUEL J. ADE DAWODU

Tailor and Draper

27, Daddy Alaja Street,

Perfect Fittings Guaranteed.

NOTICE.

When replying advertisers, please mention "Eko Akete"

---

AKIYESI.

Ti ẹ ba fẹ lọ si ọdọ awọn ti o polowo ọja sinu Iwe-irohin yi, ẹ jare ẹ sọ pe ninu iwe-irohin Eko Akete ni ẹ ti ri ipolowo ọja na ka.

---

Ọgbẹni H. CAMPOS,

Oniṣowo ni 7, Campbell, Street L'Eko. ni wai iwọsi oniruru onjẹ-panu (*Provisions*) ni tita: Ṣẹrẹkẹ ṣin ni awọn Itan-Ẹlẹde (*Hams*) ti o ni: Ọti *Wine* ati awọn Ọti miran to ni nda ni l' ọrun;

Ẹ tete lọra ti nyin nibẹ; awọn Ile-ọja rẹ miran tun mbẹ ni 63, Ọdunlami Street ati 2, Onikẹpọ Street Ita Faji l'Eko

Ohun a jẹ lo mba ni lọ.

---

"EKO AKETE"

A le ri Iwe-Irohin yi ra lọdọ awọn Aṣoju wa wọnyi.

LAGOS.

1. Ajenifuja Stores, 109 Broad Street.

Ọgbẹni VIDAL R. COLE.

EBUTE MẸTA.

Ọgbẹni S. A. Yewande, Griffith Street.

BADAGRY.

Ọgbẹni A. G. Cadmus, Ganho Street.

IBADAN.

Ọgbẹni A. M. Suberu Santo's House, Gbagi Street.

ZARIA.

Ọgbẹni A. Ekundayọ Cole, Accounts Office.

---

Are you suffering from impotent sexual & nervous prostration and impaired vitality. Use Muiracithin pills and get instant relief. It makes a man a man. In short it will rejuvenate you, also unsurpassed remedy for female Neniasthenia. Disturbed menstruation, sterlity, etc., etc. Its effect is sure and permanent, in bottle of 50 pills 5/- in bottle of 100 pills 7/- are you a sufferer of that troublesome Asthma? Why dont you use Asthamacid and get rid of it at once, in bottle 5/6. These medicines are German preparations and always give satisfactory results.

"Ajenifuja" Store
P. O. Box 201 ;109

VIDAL R. COLE
Broad Street Lagos

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

**ROMAN CATHOLIC (HOLY CROSS)**

Masses will be sung by Priests appointed.
Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi. (MORNING)

Masses Isin Aro,

6.30—7.30 8.30—9.30
7.30—8.30 9.30—10.30.

(EVENING.)

Masses (Benediction) Isin Ibukun.
4.45—5.30 6.45—7.30.

St. Michael's (Lafiaji.)

MORNING. 7 a.m.—8 a.m. 8.30 a.m.—9.30 a.m.
EVENNING. 5.45—6.30 p.m.

**ANGLICAN**

| Time. | Preacher. |
|---|---|
| 9 a.m.—Christ Church | The Vicar |
| 6.30 p.m. | do. do. |
| 9 a.m.—St. Paul's (Breadfruit) | Ven. Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi |
| 6.30 p.m. | do do |
| 9 a.m.—St. John's (Arọlọya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 6.30 p.m. | do do |
| 9 a.m. & 4 p.m.-St. Peter's (Alapako) | Rev. J. A. Cole |
| 9 a.m. & 6.30 p.m.—Holy Trinity (Ebute Ero) | Rev. S. J. Gansallo. |
| 9 a.m....St. David's (Jordan) | Rev. J. A. Leigh |

**WESLEYAN**

| | |
|---|---|
| 10.30 a.m.—Tinubu | Rev. W. F. Mellor |
| 7 p.m. | Rev. D. K. Loko |
| 10.30 a.m.—Ereko | Rev. J. F. Kufeji |
| 7 p.m. | Rev. O. A. George |
| 10.30 a.m.—Olowogbowo | Rev. N. A. B John |
| 7 p.m. | Rev. Nightingale |
| 10.30 a.m.—Obun Eko | |
| 7 p.m. | |

**AFRICAN (COMMUNION)**

| | |
|---|---|
| 9 a.m.—Jehovah Shalom | Bro. J. T. A. White |
| 7 p.m. | Rev. J. F. Ogunko |
| 9 a.m.—Bethel | Rev. Oyetunji Ọlorunjubẹ |
| 6.30 p.m. | Rev. O. Adetolu |
| 10.30 a.m.—African Methodist | Rev. Suptd. S. A. Coker |
| 4.30 p.m. | Rev. M. B. Newton |
| 9 a.m.—Ararọmi (Baptist) | Bro. D. Winsheson |
| 4 p.m. | Rev. A. A. Puddicombe |

**EBENEZER (BAPTIST)**

| | |
|---|---|
| 9 a.m. | Bro. J. J. Tubi |
| 6.30 p.m. | Bro. J. Apena |

**BROTHERHOOD**

| | |
|---|---|
| 7.30 a.m.—Ilupesi | Bro. Arinọla Ọkọya |
| 7 p.m. | Pastor A. Adedeji Iṣọla |

**St. STEPHEN'S (EPETEDO)**

9 a.m. & 4 p.m. Very Rev. J. G. Campbell

**AHMADIA (ISLAM)**

6 a.m.—Fajir Service Bro. Y. P. O. Ṣodeinde
5-30 p.m.—Open Air Service Imam K. R. Ajose (Bamgboṣe Street.)

**COLONIAL CHURCH. (ODAN)**

8 a.m.—Holy Communion Rev. H. A. Lewis
6.45 p.m.—Evensong and Sermon do

---


## BUTTER NYAJU!

Ohun jijẹ kan ti o na Butter jẹ ti a npe ni "MAGARINE"

Ọlọja Agba Ayinrin

ti gbogbo enia nsure si, wa fun tita ni Ile awọn t Oyinbo Oniṣowo,

STANDARD COMPANY OF NIGERIA LTD.

Ni Ibode lailai (Custom Street) L'Eko

Ṣile kan pere ni panu kọkan; o ṣe anfani ti a ba ko ni giri. Ọja na pọ to Iyẹpẹ, ṣugbọn bẹ lo si ka-yin to.

Yara lọ ra tirẹ nibẹ, bi bẹkọ, afara nja ọ.

---

## Ọgbẹni ERIC: JOS: W. LEWIS.

Jẹ ẹniti o gba iwe-aṣẹ Ogun pipo, o ṣi "Ṣabu" Egbogi Oyinbo si 14, Ita Tinubu nile ọgbẹni J. L. Williams Ologbe, ati si 34, Ita Ọbadina l'Eko

Ọgbẹni na ṣetan lati da enia lohun lọna iṣẹ rẹ.

Lati *Monday* de *Saturday*.

7.30 a.m de 12.30 p.m 2 p.m de 8 p.m

Ni ọjọ ọsẹ lati 6.30 a.m de 8.30 a.m

Owo to ngba ko ta enia lara, ẹ lọ bẹwo,

Ogun rẹ jire.

---

## "YESTA" SEWING MACHINES.

Nos. 3 and 4 Treadle on sale at No. 12 Odufẹgẹ Street, Ọbadina District Lagos,

At a giving-away price.

A call will convince you.

ALHAJI ỌLỌRUN-NI-[illegible]

*General Trad[illegible]*

## "O ṢE 'WỌ NI!" (FAIR WARNING)

Ọgbẹni A. W. Olukolu Onigbanjo to gba Aṣẹ ọdọ Ijọba *Nigeria*, nta orişirişi ọja ni Gbanjo, nile Gbanjo rẹ ni 2, Isalẹgangan Street, l'Eko.

O si nta ile ati ilẹ pẹlu.

Awọn ọjọ ọja-tita ni iwọnyi. Monday, ati Thursday, lagogo mẹta ọsan. Saturday, lagogo mẹsan arọ, lọsọsẹ. O ntete san owo ọja fun enia. Mu ọja rẹ lọ si bẹ.

---

**N. V. HANDELMATTSCHAPPIJ V. H.**

## J. F. SICK ati Awọn Ẹgbẹ.

No. 7, Ita Ibode lailai, l' eti *Glover Memorial Hall* (*Customs Street*,) EKO.

Awọn Oyinbo onişowo yi nranşẹ MAŞINI-ARANŞỌ ti a npe ni VESTA Nos. 1-4 t' ọlọwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju, a le fi iye-owo wọn han ẹnikẹni to ba lọ si Ile-Owo yi.

Nwọn mura tan lati ṣe adehun pataki pẹlu ẹnikẹni to ba fẹ ranşẹ Mejila tabi ju bẹ lọ ninu MAŞINI na.

Awọn Oyinbo yi nşe orişirişi Ilẹkẹ alarabara. Nwọn si nranşẹ (*Cement*) ati panu kikọle to nipọn, ati ẹja Abọmafọ ati orişirişi ọja.

Ilẹkun Ile awọn Oyinbo yi şi nigbakugba ti enia ba fẹ lati lọ ba wọn sọrọ AŞIRI nipa Owo. IROHIN KO TO AFOJUBA.

---

## Ile Ita ¦Egbogi ti Macaulay.

(*Macaulay's Household Dispensary.*)

A nta orişirişi ogun Ilera ni Ile-ọja yi, to wa ni Popo-nla (*Broad Street*,) l' Eko ni owo pọ ọ.

Awọn Ogun bi Oku, Painkiller, Ogun Inarun, Ogun Lakuregbe, Ogun Kuruna, Ogun Aran to dara Ogun Ẹda, Ogun Arẹmọ.

Ọgbọni S. A. Q. Macaulay ẹniti oni Ile-Egbogi yi jẹ ẹniti o gba Aşẹ ogun pipo (*Certificated Dispenser.*) lọwọ Ijọba Nigeria.

**Ẹ LỌ DAN A WO, Ogun rẹ jẹ bi idan.**

## ILE OWO-ỌJA RIRANŞẸ TI AWỌN ẸGBẸ OYINBO C. F. HUTHCHINSON NI ILU OYINBO.

Ọgbẹni S. B. VINTURA, Aşoju awọn Ẹgbẹ Oyinbo yi mura tan lati ranşẹ awọn Ọja bi *Herbadashery* eyini ni Şẹda, Onini, Owu-Şẹda alarabara, Ohun-elo awọn Aranşọ, ati oniruru Ọja bawọnni lati ọdọ awọn Oyinbo rẹ ni Ilu Oyinbo ni owo pọ ọ.

Ọgbẹni na si ni awọn Akẹtẹ *(Felt)* Bata Funfun ati awọn nkan miran daradara pẹlu ni tita l' owo wọn ko ta enia laiya.

Ẹ lọ dan a wo ni Ile-Owo rẹ ni Ita Tinubu, t' kọjusi Kōtu, l' Eko.

---

## ỌGBẸNI DURO: THOMAS.

ONIŞOWO PATAKI.

Ti 55, ita Faji, l'Eko, ni orişirişi Ọja to de fun u lati Ilu Germany fun tita: awọn nkan Awo abọmafọ, Cement, Akara, ati ọpọlọpọ ọja miran.

Ẹ lọ de ibẹ, Igbo-Akan 'mọpa ni ohun to ni.

Bi ẹ ba fẹ, ẹ kọwe si i, *Number* Apoti-Iwe rẹ ni Ile ipin iwe (*General Post Office*) ni *374*. *Number* fifi-ẹrọ manamana ba a sọrọ (*Telephone*) ni 243.

---

## ỌGBẸNI J. C. VAUGHAN.

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun kikọle fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nşowo Irin Işẹ lorişirişi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awọn onişowo Irin Işẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ ọ.

---

## ILE EGBOGI IŞẸ OLODUMARE.

A şi ile Egbogi kan ti a npe ni Işẹ Olodumare si ọja Ọbun Eko ni ile kẹta si Iga Oloye Aromirẹ. Nibẹ ni a le ri orişirişi iwosan fun oniruru aisan,

Ibaşe fun Orififọ, Inuririn, Ẹda, Inarun, Aran Kinnişa, Ikọ, Ipa, Ọrẹrẹ, Ọşẹ [illegible], Egbogi Oju, ati awọn Oniruru ti a ko le to sihin tan.

Rin de bẹ ki o wo o. Irohin ko to afojuba.
Iwọ ko tilẹ gbọ oruko rẹ ridan?
Işẹ Olodunmare !!!

JOSHUA O. ADE: CRAIG,
*Alabojuto.*

## ALASE LEATHER FACTORY.

"ILE ALAWỌ."

Sole-Leather tanned in a most modern style and Upper-Leather prepared in all colours, namely:—Black, White, Red, Yellow and Green, are obtainable at very cheap prices.




Awọ Bata ni ọpọku ọyọku. Kọwe ṣowọ yala ni ede Yoruba tabi ti Gẹsi pẹlu owo si:—

E. B. BEYIOKU-ALASẸ
106, Moloney Bridge St.
P. O. Box 368, Lagos, Nigeria.
*Telegrams*:—Alawọbata, Eko.

## F. BLACKBURN & Co.

Jẹ awọn Oyinbo oniṣowo ti nwọn ni ọpọlọpọ nkan atata ti ẹnu nje lotiṣirisi fun tita. Nwọn si ni awọn Asọ JOJO ni oniruru to tete nlọ ni 'le.

Ẹ lọ ke si wọn ni Ile-owo wọn.

Ni 45, Marina, L'-ko.

Awọn AWO ati IFE jojo ti a sọ ni "Macaulay m' Oluwa m' Ọba." ṣeṣe de fun tita lọdọ Ajibabi ni 89 Ita Apongbon l' Eko. Irufẹ awo ati Ife yi ko wọpọ. Ẹ lọ ba orire nyin pade nibẹ. Kosi bo ti ri ni.

AWỌN EGBE OYINBO ỌNISOWO TI A NPE
E. H. STEIN ARA HAMBURG.
NEUERWALL 16 18. GERMANY.

Jẹ Awọn oniṣowo ti Ilẹ enia dudu, nwọn nranṣẹ ọja fun ẹnikẹni fo ba fẹ' ibaṣe ọja ti Ilu Germany tabi ti awọn Ilu oyinbo miran ti o wa lagbegbe England ati Germany.

Nwọn si nba enia ta Ọja bi Epo tabi Ekuro ti ba fi ranṣẹ si wọn si Ilu awọn oyinbo (*Europe*) ni owo ti o jọ enia loju.

Ko si ewu kankan ni fi fi ọja-kọja ranṣẹ si wọn lati Eko tabi Ilu miran ni *Nigeria*.

Ki ẹnikẹni to ba fẹ ba awọn oyinbo yi ṣowo lọ tabi ki o kọwe si Aṣoju wọn nibi Ọgbẹni Karimu Kọtun ti ita Ọba Dosunmu No. 3, tabi ni ibi-iṣẹ rẹ (*Office*) ni Opopo-nla (*Broad Street*) ati ni ibi-ifi Ọja pamọ si (*Porto-novo Market Store*) L' Eko.

Ẹnikẹni le kọwe ni ede Gẹsi, niti *German* tabi niti *French*.

Oruko adugbo awọn Oyinbo oniṣowo yi ni ede *Wire* ni STEINAFRIK. Hamburg.

## GIDIGBO! GIDIGBO!! HEYA!!!



Awọn RECORDS to nkọrin lede YORUBA pọ to wọbu ni ile owo,

MANN POOLE & COMPANY LTD.,
8, TINUBU SQUARE, LAGOS.

Ki la ti nṣ' oku l' ọrun?
Ki la ti nṣ' ori nile Iku?
Tutu tabi Gbigbẹ?
Ọpọkuyọku si ni, wa ṣa eyi to wu ọ ni:—
8, TINUBU SQUARE, LAGOS.


PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.